ÀTẸ ÀKÓÓNÚ

ORÍ KÌÍNÍ: ÌFÁÀRÀ
1. Ìpìlẹ̀ ìwádìí
2. Ìṣòro tó ṣúyọ
3. Èrèdí ìwádìí
4. Pàtàkì iṣẹ́ ìwádìí

ORÍ KEJÌ: ÀGBÉYẸ̀WÒ LÍTÍRÉṢỌ̀
1.Ìfáàrà
2.Àwọn iṣẹ́ tí a yẹ̀wò
3. Líla àwọn orí ọ̀rọ̀ lẹ́sẹlẹ́sẹ
4. Ìsọnísókí àti àkíyèsí

ORÍ KẸTA: ỌGBỌ́N ÌWÁDÌÍ
1. Ìlànà ìwádìí
2. Àpẹẹrẹ ìgbẹ́sẹ̀ ìwádìí
3. Ohun-èlò ìwádìí
4. Ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ohun-èlò ìwádìí
6. Àmúlò ohun àkójọ́ fún ìwádìí
7. Àtúpalẹ̀ ohun àkójọ fún ìwádìí

ORÍ KẸRIN: ÀBÁJÁDE ÀTI ÌJÍRÒRÒ
1. Àbájáde lórí àtẹ
2. Àlàyé ṣókí nípa àtẹ
3. Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa àwọn àbájáde

ORÍ KARUN: ÌSỌNÍSÓKÍ, ÌGÚNLẸ̀ ÀTI ÀBÁ
1. Ìsọnísókí iṣẹ́ ìwádìí
2. Ìgúnlẹ̀
3. Àbá
4. Ìdènà tí a bá pàdé nínú iṣẹ́ ìwádìí, ìtọ́kásí, ìfikún

ORÍ KÌÍNÍ

ÌFÁÀRÀ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní; orúkọ ọmọ nìjánu ọmọ. Àwọn Yorùbá ka orúkọ sí púpọ̀. Orúkọ ni a fí ń dá ọmọ tó dáràn àti èyí tí ó kógo já mọ̀ ní àwùjọ. Nítorí ìdí ni wọ́n ṣe ń fi ẹja, eku, owó, omi, oyin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ láti ṣe ìkọ́mọjáde tàbí ìsọmọlórúkọ.

Àwọn Yorùbá ní ìdí tí wọ́n fí ń sọmọlórúkọ bí kò jẹ́ orúkọ àmútọ̀runwá, àbísọ, oríkì, ìdílé, oyè tàbí inágíjẹ̀. bí àpẹẹrẹ Bámidélé, Abíọ́nà, Ayọ̀mídé, Olúwatóyìn, Adébísí, Adékúnlé, Adéjùmọ̀bí.

Bákan náà ẹ̀wẹ̀ ṣé ilé là á wò ká tó sọmọlórúkọ, ìdílé tí a ti jáde ní ilẹ̀ Yorùbá ṣe kókó, ó ṣe pàtàkì. Bí ọmọ bá sọnù wọn a ní ilé ibo ló ti wá, ibo ni ká wá a sí. Tí ọ̀dọ́mọkùnrin bá fẹ́ níyàwó tàbí tí ọmọbìnrin bá fẹ́ yan ọkọ. Wọ́n a ní ilé ibo ló ti jáde? bẹ́ẹ̀ sì ni onírúurú ìdílé ni ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá bí ìdílé ọba, ìjòyè, Balógun, Ìkòyí, Ìrèmògún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní ilẹ̀ Yorùbá ìdílé kan tàbí àpapọ̀ ìdílé lè ní àdúgbò kan ṣoṣo èyí tí a mọ̀ wọ́n mọ̀ tí a sì lè pè wọ́n mọ́n ọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àdúgbò gbóòrò ju ìdílé lọ, ìdílé gbóòrò ju orúkọ lọ nígbà tí ìlú gbóòrò ju mẹ́tẹ̀ta lọ. Àpẹẹrẹ ìlú lè jẹ́ Ìlọrin, Ọ̀ṣun tàbí Ìbàdàn. Bẹ́ẹ̀ sì ni àdúgbò lè jẹ́ Kúdímọ̀ tàbí Mákọ̀lá ní ìlú Ìbàdàn, Kí àdúgbò jẹ́ àgbajì tàbí ilé Ṣọdẹ ní ìlú Ìbàdàn.

Ju gbogbo ẹ̀ lọ, kò sí orúkọ tí a lè fún ọmọ, ìdílé, àdúgbò tàbí ìlú tí kò ní ìdí kan pàtó tí irúfẹ́ orúkọ bẹ́ẹ̀ fi wáyé. Àwọn ìpìlẹ̀ orúkọ wọ̀nyí ni wọ́n ní ìrònú, ẹ̀hónú àti ìṣẹ̀lẹ̀ ìdí abájọ, bóyá nípa iṣẹ́, ìṣe tàbí àṣà. Bí àpẹẹrẹ èyí tó jẹmọ́ iṣẹ́ ní ìlú Ìlọrin, a ní ilé onígbẹ̀gìrì, onímọ́sà, ẹlẹ́ja, onílù, aláta, aládìyẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Nípaṣẹ̀ ìṣe a rí ilé bí ilé akirimọ́nú, gbágírímọ́jó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn orúkọ tí a ṣàfihàn wọ̀nyí tí a bá wo ẹ̀kọ́ Mofọ́lọ́jì, èyí tí ó tún jẹ́ ẹ̀kọ́ Mọ́fíìmù yóò tọ́ wa sọ́nà bí a ó ti ṣe ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ lọ́nà tó gún régé.

ÌṢÒRO TÓ ṢÚYỌ

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn kódà àwọn tí ó jẹ́ ọmọ ìlú Ìlọrin nílé àti lókè òkun ni kò mọ̀ nípa orúkọ, ìdílé, àdúgbò ìlú Ìlọrin dé bi pé wọn ó wá lọ mọ ẹ̀kọ́ Mofọ́lọ́jì ṣùgbọ́n tí wọ́n ń pèé tí wọ́n sì bá wọn ń pèé bẹ́ẹ̀. Nítorí ìdí èyí iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò tan ìmọ́lẹ̀ ìjìnlẹ̀ sí òye àwọn akẹ́kọ̀ọ́, àwọn ọmọ ìlú Ìlọrin àti olùgbé rẹ̀ yóò sì tún lè fikún ẹ̀kọ́ Mofọ́lọ́jì tí ó dàbí ìṣòro.

ÈRÈDÍ ÌWÁDÌÍ

Èrèdí iṣẹ́ yìí ni láti lè fikún ìmọ̀ mọfọ́lọ́jì Yorùbá nípaṣẹ̀ ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àwọn ilé, àdúgbò tí ó wà ní ìlú Ìlọrin.

PÀTÀKÌ IṢẸ́ ÌWÁDÌÍ

Pàtàkì iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ṣíṣe àwòfín àti pàtàkì ètó ẹ̀kọ́ mofọ́lọ́jì Yorùbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn baba ńlá wa tí wọ́n fún lórúkọ yálà orúkọ ènìyàn, ìdílé, àdúgbò tàbí ìlú ni wọn ò ní òye pé a lè lò ó mọ́ ẹ̀kọ́ mọfọ́lọ́jì.

Nínú ètò ọrọ̀-ajé, ìtàn, ìṣẹ̀lẹ̀ ìdí abájọ ló fa kòmóòkun ọ̀pọ̀lọpọ̀ orúkọ tí à ń fún ènìyàn, ìdílé, àdúgbò tàbí ìlú. Bákan náà iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò jẹ́ ìwúrí ńlańlá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti sí wọn ní ọpọlọ pé nínú orúkọ jíjẹ, àdúgbò, ìdílé, ìlú ni a lè ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ lórí ẹ̀kọ́ mofọ́lọ́jì.

Pàtàkì iṣẹ́ ìwádìí yìí pàápàá jùlọ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ni láti fi ní òye tí ó tayọ lórí lílo ìtàn ìlú ìlọrin àti àdúgbò rẹ̀ lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan mọ ètò ẹ̀kọ́ mofọ́lọ́jì Yorùbá

ORÍ KEJÌ

ÀGBÉYẸ̀WÒ LÍTÍRÉṢỌ̀

ÌFÁÀRÀ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n ni kì í jẹ́ kí á pé àgbà ní wèrè. Èyí ni ó fà á tí a ó fi ṣàmúlò ọgbọ́n àti ìmọ̀ nípa orí iṣẹ́ ìwádìí yìí láti lè jẹ́ kí iṣẹ́ ìwádìí gbé oúnjẹ fún ẹgbẹ́ gbàwo bọ̀. ó ṣe pàtàkì láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìmọ̀ àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n nínú èdè Yorùbá lórí orí ọ̀rọ̀ ìwádìí. A lérò pé ṣíṣe báyìí yóò ràn wá lọ́wọ́ láti wá ojútùú sí iṣẹ́ ìwádìí yìí.

ÀWỌN IṢẸ́ TÍ A YẸ̀WÒ

Ọ̀pọ̀ nínú àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n àti onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ẹ̀kọ́ mofọ́lọ́jì, a ó sì ṣe àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ wọn lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ ní orí yìí àti àwọn oríkì tí wọ́n fún un.

Awóyalé Yíwọlé(1978:5) ṣe àlàyé wí pé Mofọ́lọ́jì ni ẹ̀kọ́ nípa ẹ̀hun ọ̀rọ̀ nínú èdè kan.

Ayọ̀ bámgbóṣé(1967:37) sọ pé: Mofọ́lọ́jì ni ó ń fi ètò àti ìlànà tí ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ ń gbà wáyé hàn.

Yusuf ọrẹ(2011:66) sọ báyìí pé: morphology is the study of the structure words. When words are broken down into their utmost grammatical components.

Mofọ́lọ́jì ni ẹ̀kọ́ ìhun ọ̀rọ̀ léyìí tí àwọn ọ̀rọ̀ náà ṣeé fọ́ sí wẹ́wẹ́, tí ó sì ní iṣẹ́ tí ó ń ṣe nínú gírámà.

Awóbùlúyì(2001:47) ṣàlàyé pé: Mofọ́lọ́jì ni àwọn ọ̀nà gbogbo tí a gbà ṣẹ̀dá àwọn ẹyẹ ọ̀rọ̀ inú èdè kọ̀ọ̀kan àti onírúurú wúnrẹ̀n tí a lò fi ṣe bẹ́ẹ̀.

Kókó ohun tí àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n yìí ń sọ ni pé mofọ́lọ́jì ni ẹ̀kọ́ tí ó ń sọ nípa bí a ti ṣe ń hun ọ̀rọ̀ nínú èdè kan.

Àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n mìíràn tún sọ pé mọfọ́lọ́jì ni ẹ̀kọ́ mọ́fíìmù, bẹ́ẹ̀ sì ni oríṣìíríṣìí oríkì ni àwọn onímọ̀ ti fún mọ́fíìmù. Lára àwọn oríkì tí wọ́n fún mọ́fíìmù nìwọ̀nyí.

Ọládélé Awóbùlúyí(2007) ṣe ṣàlàyé pé: Mọ́fíìmù ni ẹ̀ya ara tí ó ní ìtumọ̀ tirẹ̀, tí kò sí ṣeé tú palẹ̀ láìpa ìtumọ̀ rẹ̀ lára. ni a mọ̀ sí mọ́fíìmù.

Ọmọ́tóyè S.O(1990) sọ pé: Mọ́fíìmù ni ègé tí ó kéré jù tí ó ní ìtumọ̀, tí ó sì tún ní iṣẹ́ tí ó ń ṣe nínú gírámà èdè náà.

Ele-Bọ́lájí W.A(2002) sọ pé: Mọ́fíìmù ni ègé ọ̀rọ̀ tí ó ní ìtumọ̀ tí ó sì wà nínú gírámà èdè kan, àmọ́ tí a kò lè fọ́ sí wẹ́wẹ́ mọ́ kí ó má baà dà ìtumọ̀ rẹ̀ nù.

Oríṣìíríṣìí mọ́fíìmù tí ó wà nínú èdè Yorùbá.
Ọ̀nà méjì pàtàkì ni a lè pín mọ́fíìmù èdè Yorùbá sí.

(i) Mọ́fíìmù adádúró tàbí ìpìlẹ̀
(ii) Mọ́fíìmù afarahẹ tàbí ìṣẹ̀dá

(i) Mọ́fíìmù adádúró tàbí ìpìlẹ̀: Àwọn ìsọ̀rí mọ́fíìmù yìí lè dá dúró fún ara wọn pẹ̀lú ìtumọ̀ kíkún. Wọ́n lè dá dúró láìsí amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tí wọ́n ó sì ní ìtumọ̀ kíkún pẹ̀lú. Ó dàbí ẹni pé àwọn mọ́fíìmù tàbí ọ̀rọ̀ yìí ti ní ìtumọ̀ odidi láti àárọ̀ ọjọ́ wá láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ wọn wá. Ìdí nìyìí tí a fí ń pè wọ́n ní mọ́fíìmù ìpìlẹ̀.

Àpẹẹrẹ irú mọ́fíìmù yìí ni ọ̀rọ̀ bíi __ Owó, Ọmọ, Ilé, Aṣọ, Wá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

(ii) Mọ́fíìmù afarahẹ tàbí ìṣẹ̀dá: Àwọn wọ̀nyí ni ègé tàbí mọ́fíìmù àfòmọ́, irú àwọn mọ́fíìmù yìí kìí sáábà ní ìtumọ̀ nígbà tí wọ́n dá wà lọ́tọ̀ àyàfi ìgbà tí wọ́n bá fò mọ́ mọ́fíìmù adádúró tàbí ìpìlẹ̀ kí wọ́n tó ní ìtumọ̀. Irú àwọn mọ́fíìmù yìí ni a fi máa ń ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tàbí àpólà ọ̀rọ̀.
Bí àpẹẹrẹ

(i)Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ + ọ̀rọ̀ ìṣe = ọ̀rọ̀ orúkọ
I + fẹ́ = Ìfẹ́

(ii)Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀+ ọ̀rọ̀ ìṣe = ọ̀rọ̀ orúkọ
Ọ + gbọ́n = Ọgbọ́n

Ọládélé Awóbùlúyì(2007) ṣàlàyé pé; Àwọn mọ́fíìmù inú èdè ọmọnìyàn pé orísìírísìí ṣùgbọ́n ní àkọ́kọ́ ọ̀nà méjì ni wọ́n pín sí. Ọ̀kan ni ti àwọn mọ́fíìmù adádúró, èkejì sì ni ti àwọn mọ́fíìmù afarahẹ

1. ÀWỌN MỌ́FÍÌMÙ ADÁDÚRÓ
Àwọn mọ́fíìmù abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni àwọn wúnrẹ̀n tí kò gba àtamọ́ kankan sára, tí wọ́n dì ṣeé lò gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ nínú ìpèdè tàbí gbólóhùn. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe ni ó pọ̀ jù nínú irú àwọn wúnrẹ̀n bá wọ̀nyí nínú èdè Yorùbá. Àpẹẹrẹ wọn ni: wá, rí, gbé, kú, kí, gé, kó, jó, jẹ́, gbẹ, jẹ, rẹ, rọ, kọ, jọ, sọ, ṣe, re, he, le, lẹ, họ, bọ̀, rọ̀, gọ̀, gẹ̀, rẹ̀, tẹ̀, tò, wò, rò, fò, jò, jì, mì, sì, ṣì, sò, mọ̀, tàn, kùn, kàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Abẹ́ ìsọ̀rí yìí náà ni àwọn arọ́pò-orúkọ wọ̀nyí wà: mi, o, ẹ, a, wa, yín, wọn. ibẹ̀ náà ni a rò (èyí kì í ṣe ohin tí ó dá wa lójú o) pé ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ wà ìyẹn àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ bí epo, oko, ilé, ọ̀rọ̀, ojú, ẹnu, àgbàdo, aṣọ, igi, ara àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

2. ÀWỌN MỌ́FÍÌMÙ AFARAHẸ
Afarahẹ ni gbogbo àwọn wúnrẹ̀n tí kì í jẹyọ àfi bí a bá lò wọ́n láti fi ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ: a, e, ẹ, i, o, ọ, oní, òǹ, àti, olú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

BÁTÀNÌ MỌ́FÍÌMÙ AFARAHẸ/ÌṢẸ̀DÁ
Àwọn ọ̀nà tí mọ́fíìmù afarahẹ ti lè jẹyọ pọ̀, àmọ́ díẹ̀ nínú wọn nìyí:

1. Wọ́n lè jẹ́ fáwẹ̀lì onísílébù kan

Àfọ̀mọ́ ìbẹ̀rẹ̀ + ọ̀rọ̀ ìṣe = ọ̀rọ̀ orúkọ
Ì + fẹ́ = ìfẹ́
È + tò = ètò
A + dé = Adé
Ọ + gbọ́n = ọgbọ́n

2. Wọ́n lè jẹ́ fáwẹ̀lì onísílébù méjì, èyí ni pé kí fáwẹ̀lì méjì papọ̀
Bí àpẹẹrẹ.

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ onísílébù méjì + ọ̀rọ̀ ìṣe= ọrọ orúkọ
Àì + jẹ = àìjẹ
Àì + mu = àìmu
Àì + sùn = àìsùn

Àì + kú = àìkú

3. Wọ́n tùn lè jẹ́ bátànì as-ọ̀rọ̀-pọ̀(Asọ̀rọ̀pọ̀)
Bí àpẹẹrẹ

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ asọ̀rọ̀pọ̀ + ọ̀rọ̀ ìṣe= ọ̀rọ̀ orúkọ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Àti | + | jẹ | = àtijẹ |
| Àti | + | mu | = àtimu |
| Àti | + | lọ | = àtilọ |

4. Wọ́n lè jẹ́ bátànì "olú" tàbí "òǹ"
Bí àpẹẹrẹ

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ olú + ọ̀rọ̀ ìṣe = ọ̀rọ̀ orúkọ

| | | |
|---|---|---|
| Olú | + sọ́ | = Olùsọ́ |
| Olú | + kọ́ | = Olùkọ́ |
| Olú | + gbọ́ | = Olùgbọ́ |

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ òǹ + ọ̀rọ̀ ìṣe = ọ̀rọ̀ orúkọ

| | | |
|---|---|---|
| Òǹ | + tẹ̀ | = òǹtẹ̀ |
| Òǹ | + fà | = òǹfà |
| Oǹ | + kà | = òǹkà |

5. Wọ́n tún lè jẹ́ bátànì "oní"

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ oní + ọ̀rọ̀ orúkọ = ọ̀rọ̀ orúkọ

| | | |
|---|---|---|
| Oní | + igi | = Onígi |
| Oní | + Ọ̀run | =Ọlọ́run |
| Oní | + ilé | = Onílé |
| Oní | + Òní | = Olónìí |

6. Wọ́n sì tún lè jẹ́ ti "kí" tàbí "ní"
Bí àpẹẹrẹ

Ọ̀rọ̀ orúkọ + àfòmọ́ àárín + ọ̀rọ̀ orúkọ= ọ̀rọ̀ orúkọ

Ọmọ + kí + ọmọ = Ọmọkọ́mọ
Ìran + kí + ìran = Ìrankíran
Ilé + kí +Ìlé. =Ilékílé
Ọ̀pọ̀ + ni + ọ̀pọ̀ = ọ̀pọ̀lọpọ̀
Àgbà + ni + àgbà = àgbàlagbà

7. Àpètúnpè àpólà
Bí àpẹẹrẹ

Wolé+wolé= Woléwolé
Dára+dára= Dáradára
Kunlé+kunlé= Kunlékunlé

8. Àpètúnpè ẹlẹ́bẹ: èyí ni àpètúnpè ìró kọ́ńsónáǹtì tàbí sílébù kan nínú ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ kan.
Bí àpẹẹrẹ

Jẹ - jíjẹ
Lọ- lílọ
Mu- mímu

9. Ìsọdorúkọ: Èyí ni sísọ ọ̀rọ̀ di orúkọ, eléyìí lè jẹ́ sísọ gbólóhùn di orúkọ
Baba+tún+dé = Babatúndé
Ọlá+wá+ilé =Ọláwálé
Ọmọ+bá+ọlá+jí= Ọmọbọ́lájí